o ṣe aluwala fun wọn ni aluwala Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a-

Lati ọdọ Yahya ọmọ 'Umaaroh Al-Maaziniy o sọ pe: Mo ri ti Amru ọmọ Abu Hasan bi Abdullahi ọmọ Zaid leere nipa aluwala Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- ni o ba beere fun igba kan ti omi wa ninu ẹ, o ṣe aluwala fun wọn ni aluwala Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a-, o da omi si ọwọ rẹ lati inu igba, o fọ ọwọ rẹ mejeeji lẹẹmẹta, lẹyin naa o ti ọwọ rẹ bọ inu igba, o fi omi yọ ẹnu o si fa a simu, O si fa a sita, ni gẹẹ mẹta, lẹyin naa o ti ọwọ rẹ bọ ọ, o si fọ oju rẹ lẹẹmẹta, lẹyin naa o fọ ọwọ rẹ mejeeji ni ẹẹmeji titi de igunpa mejeeji, lẹyin naa o ti ọwọ rẹ bọ ọ, o si pa ori rẹ, o gbe mejeeji lọ si ẹyin ati ṣíwájú ni ẹẹkan, lẹyin naa, o fọ ẹsẹ rẹ mejeeji titi de kokosẹ

[O ni alaafia] [Ohun ti wọn fi ẹnu kò lé lórí ni]

Abdullahi ọmọ Zaid- ki Ọlọhun yọnu si i- ṣàlàyé bi aluwala Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- ṣe ri, pẹlu aworan ti iṣẹ, Ni o ba beere fun igba kekere kan ti omi wa ninu ẹ, O kọ́kọ́ bẹ̀rẹ̀ pẹlu fifọ ọwọ rẹ mejeeji, lẹyin naa o tẹ igba naa o si da omi, o si fọ mejeeji lẹẹmẹta si ita igba naa, Lẹyin naa o ti ọwọ rẹ bọ inu igba, o si bu omi gẹẹ mẹta, ti o n yọ ẹnu ninu gbogbo gẹẹ kọọkan ti o si n fin omi si imu ti o si n fin in sita pada, Lẹyin naa o bu omi ninu rẹ ti o si fọ oju rẹ lẹẹmẹta, Lẹyin naa o bu omi ninu rẹ ti o si fọ ọwọ rẹ mejeeji titi de igunpa mejeeji ni ẹẹmeji ẹẹmeji, Lẹyin naa, o ti ọwọ rẹ mejeeji bọ inu igba ti o si pa ori rẹ pẹlu ọwọ rẹ lati ibi ti irun rẹ ti bẹ̀rẹ̀ titi ti o fi de ipakọ rẹ ni oke ọrun, lẹyin naa, o da mejeeji pada titi o fi de aaye ti o ti bẹ̀rẹ̀ nibẹ, Lẹyin naa, o fọ ẹsẹ rẹ mejeeji pẹlu kokosẹ mejeeji.

http://www.sunnah.global/hadeeth/yo/show/3444